UK Health Security Agency

NHS

# Dàbòbo ara rẹ lọ́wọ́ ọ̀fìnkìn

Ètò abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn ní Orílẹ̀-èdè England

Ìwífún fún àwọn tó wà ní ilé-ẹ̀kọ́ Girama




Flu immunisation

Síṣe ìránlọ́wọ́ láti dàbòbo ọ́ lọ́wọ́ ọ̀fìnkìn

## Abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn wà l'ọ́fẹ̀ẹ́ fún:

Àwọn ọmọ ọdún méjì sí mẹta (l'ọ́jọ́ 31, osu kẹjọ saaju ki gbigba abẹre ajẹsara to bẹẹrẹ ni igba irẹdanu)





Àwọn ọmọ t'ọjọ ori wọn ti le lọ ile-ẹkọ (Ti wọn n wọle si Ọdun 11)

Àwọn ọmọ láti osu 6 l'ọjọ ori pẹ̀lú ipò àìlera kan tó fi wọn sí ewu gíga lọ́wọ́ ọ̀fìnkìn



Ìwífún síwájú síi lórí àwọn ọmọ tó yẹ ní ọdún kọ̀ọ̀kan ni a le rí ní: **www.nhs.uk/child-flu**



## Kíni ìdí tí mo fi gbọ́dọ̀ gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn?

Ọ̀fìnkìn le jẹ́ àìsàn tí kò máyọ̀ wá tó ńfa ibà, rirẹ gidigidi, isan àti oríkèèríkẹ̀ẹ́ ara ríro, imú dídí, ikọ́ gbigbẹ, àti ọgbẹ́ ọ̀nà-ọ̀fun. O ma nsaba bẹrẹ lati ṣe daradara laarin ọsẹ kan. Àwọn ènìyàn kan ní àwọn ìdíjú tí wọn sì yẹ kí wọ́n lọ sí ilé-ìwòsàn fún ìtọ́jú.

## Kínni àwọn àǹfàní abẹ́rẹ́ àjẹsára?

Níní abẹ́rẹ́ àjẹsára yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ láti dábòbò ọ lọ́wọ́ ohun tí o le jẹ́ àìsàn búburú. O le ràn ọ́ lọ́wọ́ láti yàgò fún pípàdánù àwọn ǹkan tó ńgbádùn àti da ètò ẹ̀kọ́ rẹ rú.

Abẹ́rẹ́ àjẹsára yóò ṣe ìránlọ́wọ́ ààbò fún ọ tako ọ̀fìnkìn àti dín ààyè títan ọ̀fìnkìn ká sí àwọn mìíràn, tí ó sì ńpadà ṣe ìránlọ́wọ́ ààbò fún ìdílé àti ọ̀rẹ́ rẹ.

## Mo ti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn ní ọdún tó kojá. Ǹjẹ́ o nílò òmíràn ní ọdún yìí?



Bẹ́ẹ̀ni; àwọn kòkòkò àìlefojúrí ọ̀fìnkìn ńpàrọ̀ ara lọ́dọọdun nítorínà abẹ́rẹ́ àjẹsára le kún ojú òsùnwọn. Fún ìdí èyí, a dádàá wípé kí ó gba tún gba abẹ́rẹ́ àjẹsára tako abẹ́rẹ́ àjẹsára ní ọdún yìí, kódà bí o bá gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ní ọdun tó kọjá.

## Báwo ni a ó ṣe gba abẹ́rẹ́ àjẹsára?

Ó má ńsábà jẹ́ gbígbà gẹ́gẹ́bi ohun fínfín sí imú. Bí ohun fínfín sí imú kò bá wúlò, a le fún ọ ní abẹ́rẹ́ kan dipo, paapaa julọ sinu isan oke apa.

## Báwo ni ohun fínfín sí imú ṣé ń siṣe?

Ohun fínfín sí imú ní àwọn kòkòkò àìlefojúrí tí kò lágbára láti dènà wọn láti fa ọ̀fìnkìn sùgbọ́n yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ láti ní àjẹsára.

Abẹ́rẹ́ àjẹsára má ń tètè sínlẹ̀ ní imú, kódà bí o bá sín lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ lẹ́yìn tí o bá ti fín, kò nílò fúnọ láti fòyà pé kò tíi siṣẹ́.

## Ǹjẹ́ àwọn ìdíjú abẹ́rẹ́ àjẹsára yìí wà?

O le máa s'omi ní imú tàbí kí imú ẹ dí, orí fífọ́, ara rírẹ̀ gbogbogbo àti àìle jẹun. Ẹ̀wẹ̀, àwọn wọ́nyí kò le rárá ju níní ọ̀fìnkìn àti ìdíjú rẹ. Àwọn ìdíjí líle kò wọ́pọ̀.

## Bí nkò bá gbádùn lọ́jọ́ náà ńkọ́?

A le dá abẹ́rẹ́ àjẹsára náà dúró bí o bá ní ibà. Bakannaa, bí o bá ni imú dídí tàbí imú tó ń s'omi gidigidi, o le dí abẹ́rẹ́ àjẹsára lọ́wọ́ láti wọ ara rẹ. Ní irú èyí, abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn le jẹ̀ súnsún síwájú títí tí àwọn ààmì àìsàn imú fi kúrò.

## Bóòni àwọn ọdọ tí wọn ní ipò àìlera ọlọ́jọ́ pípẹ́?

Bí o bá ní àìlera ọọjọ pipẹ kan tó fi ọ́ sí ewu àwọn ìdíjú líle tó ga láti ọwọ́ ọ̀fìnkìn, o gbọ́dọ̀ gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn lọ́dọọdún. Bí o bá ní ọ̀kan nínú àwọn ipọ̀ àìlera wọ̀nyí tí wọn kòsì sí nínú àwọn àkójọ tí à ńfún abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn ní ilé-ẹ̀kọ́, o le bi dókítà alábẹ GP rẹ láti fún ọ ní abẹ́rẹ́ àjẹsára náà. O tún le bí dókítà alábẹ GP rẹ láti ṣe ẹyí bí, fún àpẹẹrẹ, o kò fẹ́ dúró títí tí ètò gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára tí ile-ẹ̀kọ́ yóò fi bẹ́ẹ́rẹ́.

### Àwọn ipò àìlera ọlọ́jọ́ pípẹ́ tó fi ọ́ sínú ewu ọ̀fìnkìn síwájú síi

Àwọn ipọ̀ wọ̀nyí ni:

- Àwọn ìsòro mímí líle, bíi ikó-fee tó nílò lílo steroid ìfàsímú tàbí òògùn kóro lóòrèkóòrè
- Àwọn ipò ọkàn líle
- Ààrùn kídìnrín tàbí ẹ̀dọ̀
- Ìtọ̀ súgà
- Iṣẹ́-ara tí kò l'ágbára ní àyọrísí ipò tàbí ìtọ́jú kan pẹ̀lú òògùn bíi steroid onikoro tàbí chemotherapy
- àwọn ìsòro pẹ̀lú ọlọ inú, fún àpẹrẹ, ààsàn arunmọlégun, tàbí tí a ti yọ ọlọ inú kúrò
- àìlágbára ìkẹ́ẹ̀kọ́
- Àwọn ìsòro pẹ̀lú ètò àgbékalẹ̀ ara, bíi àìsàn ọpọlọ

Ṣe àbẹ̀wọ̀ sí **www.nhs.uk/child-flu** fún ìwífún síwájú síi.

## Ǹjẹ́ ọ̀dọ́ kankan wà tí kò gbọ́dọ̀ gba abẹ́rẹ́ àjẹsára imú?

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọmọ ti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára fínfín sí imú èyítí a le tete ati rọrun lati funni, o sí jẹ́ abẹ́rẹ́ àjẹsára tí a yàn láàyò fún àwọn ọmọ. Ẹ̀wẹ̀, àwọn ọ̀dọ́ kọ̀ọ̀kan le má le gba abẹ́rẹ́ àjẹsára fínfín sí imú (wo àlàyé nísàlẹ̀). A ó fún àwọn òbí rẹ fọ́ọ̀mù ìfọwọ́sí kan láti parí ṣáájú gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára, èyítí yóò pẹ̀lú àwọn ìbéèrè láti ṣe àyẹ̀wò bóyá ó bá ọ lára mu. Wọ́n le sọ̀rọ̀ pẹ̀lú ikọ̀ ètò abẹ́rẹ́ àjẹsára ti ilé-ẹ̀kọ́ bí wọ́n bá ní àwọn ìbèérè kankan. Bí o kò bá le gba oní fínfín sí imú, a o fún ọ ni abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn gúngún.

## Tani kò yẹ kó gba abẹ́rẹ́ àjẹsára imú?

Dípò abẹ́rẹ́ àjẹsára fínfín sí imú, o gbọ́dọ̀ gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn gúngún bí o:

- bá ńmí lemọ́lemọ́ lọ́wọ́lọ́wọ́ tàbí ti ní ìrírí mími lemọ́lemọ́ ní wákàtí 72 sẹ́yìn.
- bá ti ní iṣẹ́-ara tí kò l'ágbára rí tàbí ẹnìkan nínú ilé rẹ nílò ìyẹra sápákan nitoripe àjẹsára ti dínkù gidigidi
- bá ti ní ipò tó nílò ìtọ́jú salicylate.
- bá ti ní àtunbọ̀tán anaphylactic sí gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn, tàbí ọ̀kankan nínú àwọn àkọ́jọ náà, tẹ́lẹ̀ (jú ẹyin lọ)

Àwọn ọ̀dọ́ tí wọ́n ti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára fínfín sí imú gbọ́dọ̀ yàgò fún ìfarakanra pẹ̀lú àwọn ènìyàn tóní iṣẹ́-ara tí kò l'ágbára (fún àpẹrẹ àwọn tó sẹ̀ṣẹ̀ ṣe ìpààrọ̀ mùdúnmúdùn eegun) fún bíi ọ̀sẹ̀ méjì tó tẹ̀lé gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára.

Bí o bá  seẹ̀ṣẹ̀ láti yàgò fún, o gbọ́dọ̀ gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn míràn. Bí kò bá dá ọ lójú, ṣe àyẹ̀wò pẹ̀lú ikọ̀ ètò abẹ́rẹ́ àjẹsára ti ilé-ẹ̀kọ́, tàbí nọ́ọ̀sì àbí GP ní àkókò iṣẹ́ abẹ rẹ.

## Àwọn òbí rẹ gbọ́dọ̀ bèèrè fún ìmọ̀ràn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ rẹ, bí o bá ní:

- àtunbọ̀tán àìbáramu líle (anaphylaxis) sí ẹyin ni ìgbàkan sẹ́yìn tí o nílò ìtọ́jú ìjìnlẹ̀
- Ikọ́-fee tí o ti tọ́jú pẹ̀lú òògùn kóro steroid tàbí nílò ìtọ́jú ìjìnlẹ̀ ní ilé-ìwòsàn.

## Níbo ní a ó ti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára náà?

Àwọn ọmọ t'ọjọ ori wọn ti le lọ ile-ẹkọ yóò gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ní ile-ẹkọ, pẹlu awọn anfaani siwaju sii lati gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ni awọn ile-iwosan agbegbe, fun ẹnikẹni to ba pa saa naa jẹ ni ile-ẹkọ.

A o fun awọn ọmọ to ba yẹ ti wọn n gba ẹkọ n'ile ni abẹ́rẹ́ àjẹsára náà. Iwọ ati awọn obi rẹ le gba iwifun nipa awọn eto lati Ẹka Ẹkọ Alaṣẹ Agbegbe rẹ.

O le ka iwe iwifun pelebe fun abẹrẹ ajẹsara nibi: **www.medicines.org.uk/emc/product/15790/smpc**

## Ǹjẹ́ abẹ́rẹ́ àjẹsára imú ní gẹlatini tí a gbà nínú àwọn ẹlẹ́dẹ̀ (porcine gelatine)?

Bẹẹni. Abẹ́rẹ́ àjẹsára imú ní gẹlatini to keere gan lati ọdọ awọn ẹlẹdẹ (porcine gelatine), èyítí a ti lò ní fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ òògùn pàtàkì. Gẹlatini náà ńràn ọ lọ́wọ́ láti múkí àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára náà dúró kí o ba le siṣẹ daradara.

Ohun fínfín sí imú jẹ abẹ́rẹ́ àjẹsára tí a yàn laayo fun awọn ọmọ, o si má ń tètè ati rọrun lati funni. O si le dara gidigidi ni dindin titan ofinkin kiri ku ni agbegbe. Bi o ko b agba awọn oogun tabi abẹ́rẹ́ àjẹsára to ni gẹlatini porcine ninu, abẹ́rẹ́ àjẹsára ọfinkin kan ti ko ni gẹlatini ninu wa larọwọto.

### Níbo ni mo ti le gba ìwífún síwájú síi?

Ṣe àbẹ̀wọ̀ sí **www.nhs.uk/child-flu** fún ìwífún síwájú síi. Bá ikọ̀ abẹ́rẹ́ àjẹsára ilé-ẹ̀kọ́ rẹ sọ̀rọ̀, GP rẹ, tàbí òsìṣẹ́ nọ́ọ̀sì bí o bá ní àwọn ìbéèrè kankan síwájú síi.

NHS

**www.nhs.uk/vaccinations**

© Crown copyright 2025. UK Health Security gateway number: 2024901. Product code: 25SECFLUYO Yoruba. 1P 2M May 2025 (APS). To order more copies of this leaflet please visit: www.healthpublications.gov.uk or call 0300 123 1002. That this leaflet is available in, Albanian, Arabic, Bengali, Bulgarian, Chinese (simplified), Chinese (traditional, Cantonese), Estonian, Farsi, French, Greek, Gujarati, Hindi, Latvian, Lithuanian, Nepali, Panjabi, Pashto, Polish, Portuguese, Romanian, Romany, Russian, Somali, Spanish, Tagalog, Turkish, Twi, Ukrainian, Urdu and Yiddish. Accessible versions are also available as an English large print, braille, British Sign Language video and audio version.